# 141 À Ń Wá Àwọn Ọ̀rẹ́ Àlàáfíà
## (Lúùkù 10:6)

1. Jésù pàṣẹ pé: ‘Ẹ wàásù òótọ́.’
Lójò lẹ́ẹ̀rùn, níbi gbogbo,
Ó ńsọ̀rọ̀ Jáà fáwọn èèyàn.
Jésù nífẹ̀ẹ́ àgùntàn Ọlọ́run.
Ó ńwá wọn lọ
ní òwúrọ̀ títí ’lẹ̀ fi ṣú.
Nílé délé, lópòópónà,
À ńwàásù fún gbogbo èèyàn
Pé láìpẹ́ gbogbo ìṣòro yóò dópin.

(ÈGBÈ)
*Kárí ayé*
*À ńwá àwọn ọ̀rẹ́ àlàáfíà,*
*Ó yẹ ká rí*
*Àwọn èèyàn tó fẹ́ rí’gbàlà,*
*Ká lè ríi pé*
*A sapá wa.*

2. Àkókò ńlọ, ká tẹra mọ́ṣẹ́ yìí.
Ọ̀pọ̀ èèyàn, ọ̀pọ̀ ẹ̀mí,
Là ń sapá láti gbà là.
Ìfẹ́ ló ńmú ká ṣáà máa wá wọn lọ.
À ńwo ọgbẹ́ ọkàn wọn sàn,
à ńtáyé wọn ṣe.
Nílùú délùú, lópòópónà,
Táa bá rẹ́ni tó gbọ́rọ̀ wa,
Ayọ̀ tó ńfún wa ńmú ká máa báṣẹ́ lọ.
(Ègbè)

(Tún wo Aísá. 52:7; Mát. 28:19, 20; Lúùkù 8:1; Róòmù 10:10.)

snylpnw-YR No. 141 3/15
© 2015 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania